# ÀWỌN ÌDÁNILÓJÚ M WÀÁ TÍ O GBỌ́DỌ̀ MỌ̀ NÍPA ÈTÒ SÍTÁǸPÙ OÚNJẸ

**Ìdánilójú:** Ètò Sítáǹpù Oúnjẹ kì í ṣe ètò owó ọ̀fẹ́ fún ẹni tí kò ní iṣẹ́. Ètó ìrànlọ́wọ́ fún oúnjẹ gidi tí a ṣe láti ran ẹnikẹ́ni ti ó ń ṣiṣẹ́ ṣùgbọ́n tí kò ní owó púpọ̀ láti rà tàbí jẹ oúnjẹ tí o lè ṣe ara rẹ̀ lóore.

**Ìdánilójú:** Ètò Sítáǹpù Oúnjẹ wà fún ẹnikẹ́ni tí ó bá ní ẹ̀tọ́ sí ètò yìí. Ìyẹn ní pé, ẹnikẹ́ni tí ó bá bèèrè fún àǹfààní yìí, tí ó sì yẹ láti gbà á yóò rí àwọn àǹfààní sítáǹpù oúnjẹ gbà.

**Ìdánilójú:** Sítáǹpù Oúnjẹ wà fún àwọn ènìyàn àti ẹbí tí ó tọ́ sí, pẹ̀lú àwọn arúgbó aláìlera, ẹbí tí ó ń ṣiṣẹ́, àwọn tí wọ́n ṣí kúrò ní ìlú wọn wá sí ìlú Amẹ́ríkà, àti àwọn ọmọ wọn tí a bí sí ìlú Amẹ́ríkà.

**Ìdánilójú:** Ènìyàn lè ní mọ́tò tàbí kí o ra ilé, kí ó ṣì lè gba sítáǹpù oúnjẹ. Ilé àti ilẹ̀ tí ilé wà lórí rẹ̀ ko pẹ̀lú ohun ìní tí a máa ń wò láti lè gba sítáǹpù oúnjẹ. Ètò Sítáǹpù Oúnjẹ kò sọ pé ènìyàn gbọ́dọ̀ jọ̀wọ́ ilé rẹ lọ́wọ́ fún ìjọba láti le wà nínú ètò yìí.

**Ìdánilójú:** Ní ọdún 2000, arúgbó tí ó ń dágbé gba nǹkan bíi dọ́là mẹ́tàlélógójì ní oṣù; arúgbó tì kò sì dágbé gba nǹkan bíi eéjìdínlọ́gọ́fa dọ́là lóṣù.

**Ìdánilójú:** Bí arúgbó tàbí aláìléra kò bá lè lọ sí ọ́fíìsì sítáǹpù oúnjẹ, ó lè sọ fún òṣìsẹ́ pé kí wọ́n bá òun fọ̀rọ̀wọ́rọ̀ lórí ẹ̀rọ tẹlifóònù. Ènìyàn yìí lè bẹ ẹbí, àlúfà, aládùúgbò, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ pé kí wọ́n bá òun lọ́ sí ibi ìfọ̀rọ̀wọ́rọ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí i aṣojú ìjọba. Àwọn tí wọ́n ń bèèrè fún SSI (Supplemental Security Income) àti àwọn tí wọ́n ń gba SSI lè bèèrè fún àǹfààní sítáǹpù oúnjẹ ní Ilé-Iṣẹ́ àmójútó ìlera àwọn ará ìlú.

**Ìdánilójú:** A lè yọ ìnáwó fún dọ́kítà tí ó bá ju dọ́là márùnúndínlógójì lóṣù, nínú owó oṣù ẹbí àfi bí ìńsọ́ránsì tàbí ẹlòmíírán tí kì í ṣe ara ilé ẹni bá san owó yìí fún yín. O lè yọ oye tí ó bá ju dọ́là márùnúndínlógójì.

**Ìdánilójú:** Owó tí ó ń wọlé fún ẹbí arúgbó tàbí ẹbíkẹ́bí tí ó ní arúgbó kan lè tó ẹgbẹ̀rún mẹ́ta dọ́là. Owó tí ó ń wọlé fún àwọn ẹbí mìíràn lè tó ẹgbẹ̀rún méjì dọ́là.

**Ìdánilójú:** Àwọn ẹbí lè gba sítáǹpù oúnjẹ, kí wọ́n tún gba oúnjẹ tí a máa ń gbé kiri lọ fún àwọn aláìní (Meals-on-Wheels), àǹfààní Ètò Oúnjẹ Àfikún Pàtàkì fún Àwọn óbìnrin, Àwọn Èwe, àti Àwọn Ọmọdé (Special Supplemental Nutrition Program for Women, Infants and Children - WIC), àti àǹfààní Oúnjẹ Gidi fún ọmọdé bí í Ètò Oúnjẹ Ọ̀sán ní Ilé-Ìwé (School Lunch Program).

**Ìdánilójú:** Gbígba àǹfààní Sítàǹpù Ounjẹ kò mú kí ẹbí tí ó tẹ̀lé òfin ìṣíwálùú dáradára di Ọmọ Ìjọba.

***Sítáǹpù Oúnjẹ ti Sọ Amẹ́ríkà di Alágbára.***

*Ilé-Iṣẹ́ Ohun Ọ̀gbìn ní ìlú Amẹ́ríkà (United States Department of Agriculture – USDA) jẹ́ ilé iṣẹ́ tí ó máa ń pèsè iṣẹ́ fún ẹnikẹ́ni láìsí ojú ìsájú.*